# Ojú-àmúwáyé Yorùbá nípa Obìnrin nínú Àṣàyàn Orin Sákárà Òsénì Èjìrẹ́

*Sanni Rifqat*


## Àṣamọ̀

*Orin dàbí ìlù olójú mejì, bí ó ṣe wúlò fún ẹni tó ń kọ ọ́ náà ló ní ìtumọ̀ sí ẹni tó ń gbọ́ ọ. Yorùbá máa ń fi orin pàrokò lórí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Ọ̀kẹ́-àìmoye iṣẹ́ ní àwọn onímọ̀ ti ṣe lóri orin sákárà àti ọ̀rọ̀ obìnrin ṣùgbọ́n a kò tí ì rí iṣẹ́ tí wọ́n ṣe lórí ojú-àmúwayé obìnrin nínú orin sákárà Òsénì Èjìrẹ́. Èyí ló mú wa yàn láti ṣe iṣẹ́ yìí pẹ̀lú àfojúsùn láti ṣe àyẹ̀wò àti àfàyọ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ obìnrin tó hàn nínú àwọn orin Òsénì Èjìrẹ́ mẹ́rin tí a yàn. Abala méjì ni a pín òté tí a fi ṣe iṣẹ́ ìwádìí yìí si: Àkọ́kọ́ ni láti ṣe àwàrí àti àṣàyàn àwọn àwo orin Òsénì Èjìrẹ́ tó ní i ṣe pẹ̀lú ọ̀rọ̀ obìnrin, èkejì ni ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn ìwé, átíkù inú jọ́nà àti ẹ̀rọ-ayé-lu-jára. A yan tíọ́rì ìfojú-ìbágbépọ̀-àwùjọ-wo lítíréṣọ̀ láti ṣe òdiwọ̀n nítorí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó ń jẹyọ nínú orin nípasẹ̀ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá láwùjọ ní iṣẹ́ yìí dálé. Àbájáde iṣẹ́ wa fi hàn pé, ọ̀rọ̀ nípa ìgbé-ayé àwọn obìnrin àti àjọṣepọ̀ wọn pẹ̀lú àwọn èrò àwùjọ̀ jẹ́ pàtàkì nínú àwọn orin tí a yàn. Ó hàn pé, ojú tí Òsénì Èjìrẹ́ fi ń wo àwọn obìnrin kò tako ti àwùjọ. Ó sì gbà pé àwùjọ tí kò bá ka obìnrin kún pàtàkì kò ṣe àṣeyè **àti àṣeyege**.*


***Kókó-ọ̀rọ̀:*** *orin sákárà Òsénì Èjìrẹ́, obìnrin gẹ́gẹ́ bí alátìlẹyìn, kòṣeémánìí, Ọ̀jọ̀wú àti Òpùrọ́, tíọ́rì ìbára-ẹni-gbépọ.*

## Ìfáàrà

Orin àti ìgbé-ayé ọmọnìyàn ti di máyàmí nítórí láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ìgbésí-ayé Yorùbá ni orin ti jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ewì alohùn Yorùbá. Ipa tí ó lóòrìn ni orin ń kó nínú ìgbé-ayé àti gbogbo ìdáwọ́lé ìrandíran Yorùbá. Ó fẹ́rẹ̀má sí ohun kan tó ń jẹyọ nínú ìbágbépọ̀ ọmọnìyàn tí a kò lè bá pàdé nínú orin ilẹ̀ Yorùbá, ní pàtàkì jùlọ orin sákárà. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó ń jẹyọ wọ̀nyí lè jẹ́ èrò Yorùbá nípa ọ̀rọ̀ ọmọbíbí, ìgbeyàwó, ikú, owó, tàbí ìwà ọmọlúàbí. Ó sì lè jẹ́ ọ̀rọ̀ òṣèlú, ọrọ̀-ajé, ọ̀rọ̀ ọkùnrin tàbí obìnrin yálà ní rere tàbí ìdìkejì. Àrokò ni ọ̀kọ̀rin Yorùbá sáábà máa ń fi orin pa fún àwùjọ tí wọ́n gbé orin wọn kalẹ̀ fún. Lọ́pọ̀ ìgbà kókó-ọ̀rọ̀ tí ọ̀kọrin fẹ́ pàrokò rẹ̀ ráńṣẹ́ sáwùjọ ló máa ń gbé wọn kọrin tàbí gbé àwo orin jáde, èyí sì lè pọ̀ níye nínú àwon orin kan ṣoṣo. Ọ̀kọrin lè gbé àwo orin kalẹ̀ lórí ọ̀rọ̀ ìṣèlú kí á sì bá ọ̀rọ̀ ọmọ, owó, ikú, obìnrin tàbí kókó-ọ̀rọ̀ mìíràn pàdé bíi amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó-ọ̀rọ̀ nínú àwo orin bẹ́ẹ̀. Ọ̀pọ̀ àwo orin sákárà Òsénì Èjìrẹ́ tí a tí bá ọ̀rọ̀ obìnrin pàdé ni kò wáyé nítorí obìnrin nìkan ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ obìnrin jẹyọ nípasẹ̀ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá láwùjọ àti ojú tí ọ̀kọrin yìí fi wo obìnrin.

Ààyè àti ipò pàtàkì ni Elédùmarè to obìnrin sí nínú ìṣẹ̀dá, àbùdá àti ojúṣe wọ́n nínú ẹbí àti láàrin àwùjọ. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan iṣẹ́ akadá ni àwọn onímọ̀ ti gbé kalẹ̀ láti fi èyí hàn, lára àwọn wọ̀nyí ni a ti rí Akínyẹmí (1986) ti ṣiṣẹ́ tó lóòrìn lórí ọ̀rọ̀ obìnrin. Ipò tí Ìṣọ̀lá fi àwọn ẹ̀dá-ìtàn lobìnrin nínú ìwé eré-onítàn Ẹfúnṣetánn Aníwúrà (1970), Olú Ọmọ (1983) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí ó kọ sí ni iṣẹ́ rẹ̀ yìí tẹpẹlẹ mọ́. Ipò olórí, aṣáájú àti akọni ni Ìṣọ̀lá fi àwọn ẹ̀dá-ìtàn rẹ̀ bíi Ẹfúnṣetán àti Tinubu sí nínú àwọn ìtàn rẹ̀. Èyí sì fi hàn pé obìnrin ko ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá nínú ètò ìṣèlú àti ìṣèjọba. Ó tún fi hàn pé, àwọn obìnrin inú ààfin Ọ̀yọ́ jẹ́ ìyàwó àwọn Aláàfin tó ti wàjà, bẹ́ẹ̀ ní ó tún tọ́ka ipa tí wọ́n kó nínú ètò ìṣèlú. Bí Ìṣọ̀lá ṣe wá fi obìnrin hàn tó yìí, ó sì parí ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé ọkùnrin ló jẹ́ olórí nígbà gbogbo. Ilésanmí (1989: 82) tó tọ́ka sí obìnrin pe:

> Àwọn obìnrin ni agbátẹrù ọ̀pọ̀ ewì àtẹnudẹ́nu ní ilẹ̀ Yorùbá. Wọ́n ni awo tó dabí ẹni ágbára ju awo àwọn ọkùnrin lọ. Àwọn ló ni awo ẹlẹ́ẹ̀ẹ̀rìndínlógún, àwọn ló ni awo ẹlẹyẹ; àwọn ló lẹgbẹ́ ewe; àwọn ló ni ìsàré àti orin ọ̀ṣun; àwọn ni agbátẹrù gbogbo òrìṣà tó jẹ omi…

Onímọ̀ yìí tọ́ka sí ipa pàtàkì tí àwọn obìnrin kó nínú ìdàgbàsókè ewì alohùn Yorùbá, bẹ́ẹ̀ náà ló tún tọ́ka sí àwọn ẹgbẹ́ awo tó jẹ́ àwọn obìnrin ni ògúnnágbòǹgbò nídìí wọn. Ipa tí obìnrin kó nínú orin ati ìsàré òrìṣà ọ̀ṣun kò gbẹ́yìn nínú èrò onímọ̀ yìí.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì tí a yàn láti fi ṣe ìtúpalẹ̀ ojú-ìmúwayé obìnrin nínú àwọn àṣàyàn orin Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ nínú bébà yìí ni tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ-wo lítíréṣọ̀ ti a tún mọ̀ sí tíọ́rì soṣiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀. Laurenson àti Swingwood (1971:31) tọ́ka sí i pé, “the term sociology of literature was coined by Taine, the French Philosopher and critic (1828-1893)” (ọmọ ilẹ̀ Faransé tí ó jẹ́ onímọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ àti lámèyítọ́ ni ó ṣẹ̀dá orúkọ fún tíọ́rì ìbára-ẹni-gbépọ̀). Lára àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ni Louis de Bonald (1754-1840), Escarpit (1968), Duncan àti Preminger .

Ọ̀wọ́ méjì ni àwọn onímọ̀ pín lámèétọ́ ìfojú-Ìbára-ẹni-gbépọ: Ọ̀wọ́ **àkọ́kọ́ ni àwọn tí ó gbà pé díngí ni lítíréṣọ̀ jẹ́** fun àwùjọ. Louis de Bonald (1754-1840) ni Laurenson àti Swingwood (1971:31) gbà pé ó jẹ́ agbátẹrù ọ̀wọ́ yìí. Ọ̀wọ́ kejì ni àwọn tó gbà pé lámèétọ́ gbọ́dọ̀ wo iṣẹ́-ọnà bí i okoòwò tàbí títà-rírà. Escarpit ni wọ́n tọ́ka gẹ́gẹ́ bí i agbátẹrù ọ̀wọ́ kejì yìí. Adéyẹmí (2006:32) ṣàlàyé pé, abala àkọ́kọ́ tí Louis de Bonald (1754-1840) àti àwọn ìsọmọ̀gbè rẹ̀ jẹ́ agbátẹrù fún ni wọ́n pe ìlànà tiwọn ní *Mirror Image Approach.* Ìlànà ti wọn dàbí ẹni gbé díngí kan kalẹ̀ tí a fi ń wo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí a wá ń sọ ohun tí a rí di lítíréṣọ̀. Wọ́n gbà pé, a lè mọ̀ nípa ìran kan dáadáa bí a bá farabalẹ̀ ka lítíréṣọ̀ irú àwùjọ bẹ́ẹ̀. Èyí fi

hàn pé, ohun tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ nínú àwùjọ kan ni a máa bá pàdé nínú lítíréṣọ̀ bí i orin sákárà tí ó bá ń jáde látọwọ̀ àwọn oníṣẹ́-ọnà-lítíréṣọ̀ bí i ọ̀kọrin tó bá ń gbé irú àwùjọ náà. Kókó-ọ̀rọ̀ tí wọ́n ní kí lámèyítọ́ máa wá ni bóyá ìṣẹ̀lẹ̀ kan rí bẹ́ẹ̀ lójú ayé tàbí kò rí bẹ́ẹ̀. Èrò àwọn tó ní ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ máa ń hàn nínú lítíréṣọ̀ ni a tẹ̀lé láti tan-ná wo ojú-àmúwayé Yorùbá nípa obìnrin nínú àṣàyàn orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́.

## Ọgbọ́n Ìṣèwádìí

Ṣíṣe àwàrí àti àṣàyàn àwo orin Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ tó ṣe àfihan àwọn obìnrin ni ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́. Èyí jẹ́ dandan nítorí orin wọ̀nyí gan-an ni a gbọ̀n yẹ́bẹ́yẹ́bẹ́ láti ṣe àfàyọ ojú tí olórin yìí fi wo àwọn obìnrin nínú àwọn orin sákárà rẹ̀. Ọ̀nà láti ṣiṣẹ́ tó kẹ́sẹjárí mú wa ṣe àdàkọ àwọn àwo orin tí à ṣàyàn, èyí sì mú kí ó rọrùn láti ṣe àfàyọ kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ bébà yìí lógún nínú àwọn orin náà.

A tún ṣe àyẹ̀wò sí ilé ìṣèwélọjọ láti ka onírúurú ìwé, átíkù, ìwé-ìròyìn, bẹ́ẹ̀ ni a lo ẹ̀rọ ayélujára (Internet) láti ṣe àwárí èrò tó jẹ mọ́ akòrí bébà yìí. Bákan náà, a ṣe àmúlò èrò Louis de Bonald lórí tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ láti ṣiṣẹ́ lámèyítọ́ tó péye lórí àwọn àwo orin Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ tí a yàn. Èrò onímọ̀ yìí jẹ́ kí á lè sọ ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwọn orin wọ̀nyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tó ń lọ láwùjọ tàbí ó jẹ́ irọ́. Ṣíṣe àmúlò èrò Louis de Bonald yìí tún jẹ́ kí á lè kín èrò Oyèbámijí (1975:518) lórí pé “orin sákárà kò gba ọ̀nà kankan jẹ́ mọ ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn” lẹ́yìn nítorí a lè sọ pé kì í ṣe ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn nìkan ló ń jẹyọ nínú orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́, a rí àfihàn ìwà obìnrin láwùjọ tọ́ka sí.

## Ìtàn Ìdìdélẹ̀ Orin Sákárà


Ọ̀kan-ò-jọ̀kan onímọ̀ ló ti lórí orin sákárà, èrò wọn kò sì fi gbogbo ara yàtọ̀ síra. Lára àwọn onímọ̀ ni a ti rí Euba, (1971:180), Olúkòjú (1994), Gbénró (2001:61) àti Ajíbóyè (2003:110) tí wọ́n ní èrò kan náà lórí ìtàn orírun sákárà. Wọ́n gbà pé ọmọ Yorùbá kan tó ń jẹ́ Ábúdù tó lọ ṣe àtìpó ní ìlú Bìdá ní ìpínlẹ̀ Náíjà ló pilẹ̀ orin sákárà. Ìtan náà sọ síwájú sí i pé alaalẹ́ lẹ́yìn iṣẹ́ oòjọ́ ni Ábúdù máa ń kó àwọn ọmọ Yorùbá ẹgbẹ́ rẹ̀ jọ. Wọn yóò máa fi eré kerekérè dá ara wọn láràyá, ẹnìkan nínú wọn yóò sì máa fi igi tẹ́ẹ́rẹ́ méjì lu igbá tí wọ́n dojú rẹ̀ délẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìlù. Nínú ere yìí, àwọn kan yóò máa kọrin, àwọn kan yóò sì máa jó. Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ ni wọn fi Gòjé, ọrùn-ìṣà (ọrùn ìkòkò tí a gé) tí a so awọ mọ́ lójú apá kan tí a sì ń fi igi kọ̀ǹgọ́ tàbí ọ̀pá-ìlù lù kún ohùn-èlò ìṣèré wọn. Eré yìí ti gbẹ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ kí wọn tó mú un wá sí ìlú Ìbàdàn, wọn sì ti fi igbá kékeré tó ṣe é fọwọ́ méjèèjì dìmú lọ́nà tí wọn yóò lè máa fi òrùka tó wà ní gbogbo ọmọ ìka ọwọ́ wọn lù ú dípò igbá ńlá aládojú-délẹ̀-figi-tẹ́ẹ́rẹ́-méjì-lù.

Ìtàn yìí tẹsíwájú pé, Afọlábí Agbọ́ngun láti ìlú Ọyọ́ kọ́ eré yìí lọ́wọ́ Ábúdù àti

àwọn eléré rẹ̀. Bùráímọ Kúlúḿbú sì kọ́ eré yìí lọ́wọ́ Afọlábí, òun náà sì tún kọ́ Pópó tí ó gbé orin náà jókòó ní Ìsàlẹ̀-bodè ní ìlú Ìbàdàn. Wọ́n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, ọwọ́ Pópó ni àwọn ará Ìjẹ̀bú kan tó ń gbé ní àdúgbò Ìsàlẹ̀-Bodè ní ìlú Ìbàdàn ti kọ́ eré náà, tí wọ́n sì mú un lọ sílẹ̀ Ẹ̀gbá níbi tí eré sákárà náà ti wá gbilẹ̀ ju ti Ìbàdàn àti Ìjẹ̀bú lọ.

## Díẹ̀ Lára Àwọn Ohun Èlò Orin Sákárà

Ó hàn pé inú èdè Haúsá ni Móló àti Gòjé ti wá. Ìdí tí èyí sì fi rí bẹ́ẹ̀ hàn nínú ìtàn orin sákárà tó sọ pé Ábúdù ọmọ Yorùbá tó ń ṣe àtìpó ní Bídà ló kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ orin sákárà Kò jẹ́ ìyàlẹ́nu pé ohun èlò orin Haúsá ni wọ́n ń lò fún orin Yorùbá, nítorí ìlú Haúsá ni wọ́n ti bẹ̀rẹ̀ rẹ̀.

| | |
|---|---|
|  |  |
| *Àwòrán 1: Ìyá Ìlú* | *Àwòrán 2: Gòjé* |
|  |  |
| *Àwòrán 3: Ìlù Sákárà* | *Àwòrán* 4: Inú ìlù Sákárà |

## Iṣẹ́ tí ó wà nílẹ̀ lórí Orin Sákárà

Ọkan pàtàkì ni orin sákárà láàrin orin ìbílẹ̀ Yorùbá. Oyèbámijí (1975:521-522) tọ́ka sí i pé, oríṣi mẹ́ta ni ọ̀nà àgbékalẹ̀ orin sákárà. Ìkínní ni *Ẹ̀sọ̀*, èyí tó gbayì lọ́dọ̀ àwọn ọ̀dọ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn ló nífẹ̀ẹ́ sí Ẹ̀sọ̀, ìgbésẹ̀ rẹ̀ wuyì, ó sì wà ní kánmọ́kánmọ́. *Sákárà kíkún* ni oríṣi kejì, èyí kò yá kò sì falẹ̀. Ohun ni wọ́n sì

ń pè ní ijó fàájì. Ijó rẹ̀ wà láàrin pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ àti kíákíá, èyí ni àwọn obìnrin nífẹ̀ẹ́ sí. *Àgbàlá* ni ọ̀nà àgbékalẹ orin sákárà kẹta. Ọ̀nà pẹ̀lẹ́ ni èyí ń bá wa, orin àwọn àgbàlagbà ni. Ìlànà wíwọ́ ẹsẹ̀ nílẹ̀ wẹ́rẹ́wẹ́rẹ́ ni wọ́n fi máa ń jó o. Èrò onínọ̀ yìí fi hàn pé tàgbà tọmọdé, tọkùnrin tobìnrin ló lè rí èyí tí yóò nífẹ̀ẹ́ sí nínú orin sákárà.

Èrò Adégbìtẹ (2000:32) àti Ọláníyan (2000: 77) báramu. Wọ́n sọ ọ́ di mímọ̀ fún wa pé, àwọn àgbàlagbà ló ni eré sákárà àti pé lẹ́sọ̀lẹ́sọ̀ lorin, ijó àti ìlù sákárà. Orin fàájì sì ni pẹ̀lú. Olúsọjí (2008:130) ṣiṣẹ́ lórí àgbéyẹ̀wò àwọn orin Yorùbá tí ẹ̀sìn Ìsìláàmù nípa lórí wọn. Ó fi ìdí ọ̀rọ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé, "Àpàlà, wákà and sákárà are Yorùbá musical genres that have been influenced by Islamic religion" (ẹ̀sìn Ìsìláàmù ti nípa lórí àwọn ẹ̀yà orin ìbílẹ̀ Yorùbá bí i Àpàlà, wákà àti sákárà). Èrò rẹ̀ yìí fi ìdí ọ̀rọ̀ múlẹ̀ pé ohun tó jẹmọ́ ẹ̀sìn Ìsìláàmù ti ń fara hàn nínú àwọn orin ìbílẹ̀ Yorùbá bí i Àpàlà, wákà àti sákárà. Gbénró (2001: 62) kín èrò yìí lẹ́yìn nígbà tó tọ́ka sí i pé, àwọn Mùsùlùmí ní wọ́n kọ́kọ́ dárúkọ pé wọ́n ń ṣe eré sákárà, àwọn Mùsùlùmí ló sì pọ̀jù nínú wọn. Ó fi kún àlàyé rẹ̀ pé, bóyá èyí ló fàá tí ó fi jẹ́ pé ibi ayẹyẹ àwọn Mùsùlùmí ni a ti kọ́kọ́ máa ń lo eré sákárà kí ó tó di pé gbogbo ẹlẹ́sìn yálà Ìsìláàmù, Ọmọlẹ́yìn-Kristi tàbí ẹlẹ́sìn ìbílẹ̀ wá ń lò ó.

Collins (2002) ṣàlàyé pé, ọdún ààwẹ̀ tí àwọn Mùsùlùmí máa ń ṣe ni ó bí orin sákárà ní àsìkò ogun àgbáyé àkọ́kọ́. Ọkan lára ohun èlò tí wọ́n fi ń gbé orin yìí láruge ló ni orúkọ tí wọ́n fi ń pè é. Ìlù sákárà tí wọ́n fi apẹ ṣe ni wọ́n fi fún orin náà ní orúkọ. Okùnadé (2003:217) náà sọ àsọyán ọ̀rọ̀ pé, "music forms such as àpàlà, wéré, sákárà and wákà are real Yorùbá Islamized music forms" (ẹ̀yà orin Yorùbá bí àpàlà, wéré, sákárà àti wákà ni wọ́n ti sọ di orin ẹ̀sìn Ìsìláàmù). Èrò òkè yìí fi hàn pé, awọn orin ìbílẹ̀ Yorùbá bí i Àpàlà, wéré, sákárà àti wákà ti gba ìmísí láti ara ẹ̀sìn Ìsìláàmù, ṣùgbọ́n èyí ko sọ pé wọ́n kì í ṣe orin ìbílẹ̀. Rájí (2014:34) náà fi ọ̀rọ̀ yìí múlẹ̀ pé orin ajẹmẹ́sìn Ìsìláàmù ni orin sákárà lóòótọ́ ṣùgbọn ó ti di orin tí a ń kọ níbi ayẹyẹ gbogbo yálà ti Ìsìláàmù tàbí èyí tí kì í ṣe ti Ìsìláàmù. Ipò tí àwọn orin ìgbàlódé gbogbo wà láwùjọ Yorùbá náà ni Orin sákárà wà.

## Èrò Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ Nípá Obìnrin Yorùbá

Èrò a-ṣe-búburú ṣe-rere tí àwùjọ Yorùbá ní nípa obìnrin náà ni ó fara hàn nínú àwọn orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ tí a yàn fún iṣẹ́ yìí. A rí ibi tí ọ̀kọrin ti sọ ohun rere nípa àwọn obìnrin bẹ́ẹ̀ ni a rí ibi tí ó ti tọ́ka sí ìwà aburú àwọn obìnrin bí ó ti ń jẹyọ ní àwùjọ.

### Ìwà Rere Àwọn Obìnrin Nínú Orin Òsénì Ẹ̀jìrẹ́

Ohun àti ìwà tí ó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà àwùjọ ni Yorùbá mọ̀ sí rere. Àpẹẹrẹ ìtọ́kasí ìwà rere ọwọ́ àwọn obìnrin hàn nínú àwo orin Òséní Ẹ̀jìrẹ́ lọ́kan-ò-jọ̀kan. Ojú tí

àwujọ Yorùbá mú wo ayé obìnrin fi hàn pé a lè bá àwọn ìwà rere wọ̀nyí ní ọwọ́ àwọn obìnrin:

**Obìnrin bí Alátìlẹyìn Ọkọ**

Yorùbá gbà pé ẹ̀dá kan kò lè dá ilé-ayé ṣe, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀dá nílò ìrànwọ́ àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ẹ̀dá mìíràn lati lè ṣe àṣeyọrí lọ́pọ̀ ìgbà. Bákan náà ni Yorùbá tún gbà pé olùrànlọ́wọ́ ló yẹ kí ọkọ àti ìyàwó jẹ́ fún ara wọn. Àwọn èro Yorùbá wọ̀nyí jẹyọ nínú orin Òsénì Èjìrẹ́ tí ó pe àkọ́lé rẹ̀ ní "*Ìtàn Àwórì*" báyìí:

LÍLÉ …Kúbúrà, Adéníkẹ̀ẹ́ laya tí a fẹ́
ÈGBÈ Nígbà tí a fẹ́ ẹ, tí a fẹ́ ẹ
Nígbà tí a fẹ́ ẹ, larísìkí mà ti dé
ÀJỌKỌ Ó dúró tọkọ nígbà tó ṣòro o
Ó dúró tọkọ nígbà tó ṣòro o
Ọjọ́ tí o fẹ dékọ́le o, Ògìdán kọ́lé ọlá
LÍLÉ Ó kọ́lé ọlá
ÀJỌKỌ Ìyàwó Odùṣínà
Kúbúrà Adéníkẹ̀ẹ́ alárísìkí èèyàn
LÍLÉ Ọlọ́run ò mà ní tẹ́ ẹ
ÈGBÈ Ó nítẹ́ríba púpọ̀ nínú aya
LÍLÉ Ọlọ́run ò mà ní tẹ́ ẹ
ÈGBÈ Ó nítẹ́ríba púpọ̀ nínú aya

Ọ̀kan lára èrò Yorùbá nípa àṣeyọrí ọkùnrin ni pé, bó bá fẹ́ ìyàwó rere yóò gbé ohun rere ṣe nílé-ayé. Obìnrin a máa di ẹni iyì nílé ọkọ tí ìgbé ayé ọkọ rẹ bá yípadà sí rere lẹ́yìn tí wọ́n fẹ́ ẹ níyàwó. Ọ̀kọrin fi hàn nínú àyọlò yìí pé, ní kété ti Àdéníkẹ̀ẹ́ ti di ìyàwó Òduṣína ni ó ti di olówó tí ó sì ńkọlé, tó ń ra mọ́tò. Èyí fi hàn pé ẹsẹ̀ Àdéníkẹ̀ẹ́ dára nílé ọkọ rẹ̀. Bákan náà ni ó tún tọ́ka sí obìnrin náà gẹ́gẹ́ bí ìyàwó tó ní ìtẹríba nílé ọkọ. Èrò Louis de Bonald (1754-1840) lórí tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ nínú Adéyẹmí (2006:32) tí ó tọ́ka pé, iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ dàbí ẹni gbé díńgí kan kalẹ̀ tí a fi ń wo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, tí a wá ń sọ ohun tí a rí di lítíréṣọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú àyọlò òkè yìí. Ó hàn pé èrò, ìgbàgbọ́ àti ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ Yorùbá ni ọ̀kọrin yìí gbé jáde láti fi tani jí.

## Obìnrin Gẹ́gẹ́ bí Gbajúmọ̀ Oníṣòwò

Yorùbá nífẹ̀ ẹ́ sí iṣẹ́ ṣíṣe, wọ́n kò sì ń fi ojú rere wo ọ̀lẹ èèyàn rárá. Yorùbá gbà pé, ẹ̀dá tó bá ń ṣiṣẹ́ nìkan ló lè jàré òṣì, àti pé iṣẹ́ ni oògùn iṣẹ́. Ọ̀kan pàtàkì lára iṣẹ́ tí Yorùbá gbà pé obìnrin lè ṣe ni kárà-kátà, ojú yìí náà sì ni Òsénì Èjìrẹ́ fi wò ó nínú orin rẹ̀. Ó tọ́ka sí i báyìí:

LÍLÉ Ìyálájé ọmọ Ọlọ́fin

ÈGBÈ Ta ń bá ra fọ̀ìlì
LÍLÉ Ọmọ Ọlọ́fin
ÈGBÈ Ta ń bá ra fọ̀ìlì
LÍLÉ Ó ń taṣọ
ÈGBÈ Oríṣiríṣi,
LÍLÉ Ó ń ta bàtà
ÈGBÈ Báńka ṣúù
LÍLÉ Bọ́dì ìyálájé wà
ÈGBÈ Ó dúró pa délẹ̀
LÍLÉ Mẹ̀sí ọlọ́yẹ́, ló fi ń jẹ̀gbádùn
ÀJỌKỌ Ájà Múlíká Òyéfẹ̀sọ̀ o…
Bo fẹ́ r'Amẹ́ríkà o, ko jẹ́ kí n gbọ́ oo
LÍLÉ Mo ń fẹ́ bàtà, tówó ẹ̀ bá ga jù
ÈGBÈ Àwọn bàtà, ta ń lò lásìkò
LÍLÉ Ìyẹn bàtà…

Àyọlò òkè yìí fi hàn pé oníṣòwò pàtàkì tó ń ta aṣọ léèsì àti bàtà olówó iyebíye ni Ájà Múlíká tí ọ̀kọrin ń tọ́ka sí. Bẹ́ẹ̀ ni ó hàn pé ẹni yìí ti gbé nǹkan ribiribi ṣe nípasẹ̀ kárà-kátà tó ń ṣe yìí. Ojú tí ọ̀kọrin fi wo obìnrin láàyè yìí fi hàn pé wọn kì í ṣe ẹni yẹpẹrẹ láwùjọ àti pé amúni-dára ni wọ́n jẹ́. Àjọ̀ṣepọ̀ ẹ̀dá láwùjọ ló mú èyí rọrùn tí ó sì di ohun tí ó hàn nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ bíi orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ògúnṣínà (1987) tó tọ́ka sí i pé, soṣiọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ jẹ́ àfihàn àjọ̀ṣepọ̀ tó wà láàrin lítíréṣọ̀ àti àwùjọ àtí pé a gbọ́dọ̀ wò ó mọ́ àwùjọ ni.

## Obìnrin Gẹ́gẹ́ bí i Kò-ṣe-e-má nìí

Àṣà àti ìṣe Yorùbá kò fàyè gba kí ọkùnrin tí ó ti bàlágà má ní ìyàwó lọ́ọ̀dẹ̀. Ọkùnrin tí ó bá wá tó fẹ́ ìyàwó tí kò fẹ́, a di ẹni àbùkù láwùjọ, ẹnu rẹ̀ kò sì ní í tọ́rọ̀ láàrin ẹgbẹ́ (Dáramọ́lá àti Jeje, 1975). Èyí fi hàn pé àwọn ọkùnrin mọ rírì àti ipa ribiribi tí obìnrin ń kó nínú ayé wọn. Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ fi èyí hàn nínú orin "*Òdéte-déte*" báyìí:

LÍLÉ …Iṣẹ́ la fi ń dẹni gíga, múra síṣẹ́ ọ̀rẹ́ẹ̀ mi
Àpọ́n jìyà kó tó lèé fẹ́yàwó o
Bápọ́n bá jà jà jà jà, tó bá doníyàwó nílé
Bíyàwó àpọ́n bá ń lọ sóko
Á wun àpọ́n pé kó máa báyàwó ẹ̀ lọ o
Bíyàwó àpọ́n bá ń rodò
Á wun àpọ́n pé kó máa báyàwó ẹ̀ rè
Bíyàwó àpọ́n bá ń fẹ́ná
Á wun àpọ́n pé kó máa fẹ́ díẹ̀ síná
Bó bá rántí ìyà, tó ti ń jẹ̀un bọ̀ látẹ̀yìn

Ìbànújẹ́ ò jìnnà sẹ́ni tí ó níyàwó oo
Bẹ́ẹ̀ làìlóbìnrin kò kúkú ṣe é dákẹ́

Ọ̀kọrin yìí sọ àsọyé ọ̀rọ̀ lórí ọ̀rọ̀ fífẹ́ ìyàwọ́ ṣe máa ń múmú láyà ọkùnrin tí ó bá ti bàlágà nílẹ̀ Yorùbá tó. Ó ní wàhálà tí ọkùnrin máa ń ṣe kí wọn tó rí ìyàwó fẹ́ yìí máa ń jẹ́ kí ojú má ro wọ́n, kí ó sì tún nira fún wọn láti jẹ́ kí ìyàwó wọn ṣe wàhálà tàbí kí ó jáde lọ sí ibi tí ojú àwọn ko ti ní í tó o. Èyí lè jẹ́ nítorí pé wọn kò fẹ́ kí ohun búburú bí i ikú ṣẹlẹ̀ sí i. Ó sì tún lè jẹ́ pé, wọ́n ń bẹ̀rù kí ọkùnrin mìíràn má bàá gba ìyàwó wọn, tàbí kí ó jẹ́ pé ìfẹ́ ló mú kí ọkàn wọn máa pòruru. Kò sí èyí tó jẹ́ àwáwí nínú ohun tí Òsénì Èjìrẹ́ sọ, ọ̀kọrin yìí kín èrò àwọn onímọ̀ tó tẹ̀lé ìlànà Louis de Bonald (1754-1840) sọ pé àwọn nǹkan kan máa ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ nípasẹ̀ ìbágbépọ̀ àwọn ẹ̀dá àwùjọ lẹ́yìn.

## Ìwà Búburú Àwọn Obìnrin Nínú Orin Òsénì Èjìrẹ́

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣíwájú pé, a ṣe búburú ṣe rere ni àwùjọ Yorùbá gbà pé obinrin jẹ́. Òsénì Èjìrẹ́ kò gbàgbé láti fi èyí hàn nípa títọ́ka sí àléébù àti ìwà kò tọ́ ọwọ́ àwọn obìnrin nínú orin sákárà rẹ̀. Ó tọ́ka sí ìwà aburú àwọn obìnrin lórísirísi nínú àwọn àwo rẹ̀ báyìí:

### Obìnrin Gẹ́gẹ́ bí Òjòwú

Owú jíjẹ láàrin àwọn obìnrin síra wọn kì í ṣe ohun bàbàrà láwùjọ Yorùbá. Èyi kò mọ láàrin àwọn ìyàwó tí ó jìjọ fẹ́ ọkọ kan náà. Owú lè wáyé láàrin ọmọ bàbá, ọmọ ìyá kan náà, ọ̀rẹ́ síra wọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Yorùbá gbà pé ara ìwà tí Elédùmarè dá mọ́ ẹ̀dá ni owú jíjẹ, bẹ́ẹ̀ wọ́n kò fara mọ́ owú gbígbóná. Òsénì Èjìrẹ́ fi ọ̀rọ̀ nípa owú jíjẹ hàn nínú àwo orin "*Ìwà lẹwà*" yìí

LÍLÉ Ó mú mi rántí bàbá kan o
Tó fẹ́yàwó o méjì o
Ìkan ń gbọ́ tọkọ, ìkan ò gbọ́ tọkọ…
Àwọn ìyàwo méjèèjì
Wọ́n ń pòwe síra wọn nínú ilé
Èyí tó ń gbọ́ tọkọ sọ pé
Ọkọ tó bá torí owú nà mí òóoo
Ẹ̀dá mi á ba ẹ jà àà, ọkọ
ÈGBÈ Tó bá torí owú nà mí, ẹ̀dá mi á da a fun
LÍLÉ Ṣé bí ẹ ti rí mi láṣẹ́wó, kẹ́ tó pé n wá
ÈGBÈ Ẹ̀dá mi á da a fun
LÍLÉ Ẹ mà ti rí mi ní nàbì, kẹ tó pè mí yà o
ÈGBÈ Ẹ̀dá mi á da a fun, …
LÍLÉ Ìrandíran obìnrin ló kúkú ti ń jowú
ÈGBÈ Ẹ̀dá mi á da a fun
LÍLÉ Torí tóbìnrin ò bá jowú, ọbẹ̀ kì í dùn un

ÈGBÈ Ẹ̀dá mi á da a fun

Òsénì Èjìrẹ́ fi ìdí ọ̀rọ̀ múlẹ̀ pé, ọkùnrin kan kò gbọdọ̀ bá ìyàwó rẹ̀ jà nítorí pé ó jowú orogún rẹ̀ nítorí lára ìwà àdámọ́ èèyàn ni owú jíjẹ. Àpẹẹrẹ bí obìnrin ṣe máa ń fi owú jíjẹ hàn tún jẹyọ nínú orin Òsénì Èjìrẹ́ tí ó pè ní "Mójú kúrò" báyìí:

LÍLÉ Kò lè lè tilé lọ
ÈGBÈ Kó má mà lé tilé lọ ọ
LÍLÉ Kò mà gbọdọ̀ lé tilé lọ ọ
ÀJỌKỌ Kó má mà lé tilé lọ ọ
Ìyáwo ojú-ọ̀nà kò lè lé tilé lọ
LÍLÉ Kò lè lè tilé lọ
ÈGBÈ Kó má mà lé tilé lọ ọ
LÍLÉ Tilé lọ ọ
ÈGBÈ Kò lè lè tilé lọ, kò lè lè tilé lọ
ÀJỌKỌ Ìyáwo ojú ọ̀nà kò lè lé tilé lọ ọọ
LÍLÉ Ẹni máa lọ
ÈGBÈ Kó máa lọọ…

Àyọlò òkè yìí dàbí ìkìlọ̀ fún àwọn obìnrin tí ọkùnrin ń gbèrò láti fẹ́ lé ìyàwó tilé kó rọra jowú àjọṣepọ̀ àwọn (ìyálé àti ọkọ) nítorí òun (ọkọ) ko ní lé ìyálé kúrò nílé torí pé òun ń fẹ́ ẹ. Ohun tí ó ṣe é ṣe ko fa irú orin yìí ní tí ìyàwó tó wà lọ́nà bá ń ba olólùfẹ́ rẹ̀ jà nítorí àjọṣepọ̀ àárín olólùfẹ́ rẹ̀ àti ìyàwó tàbí àwọn ìyàwó tí ó ti fẹ́ ṣáájú rẹ̀. Olórin ń fi orin yìí pòwe mọ irú obìnrin bẹ́ẹ̀ kí o rọra jowú, kí ó má bàá fi owú ba ìfẹ́ àárin àwọn jẹ́.

Àwọn àyọlò òkè wọ̀nyí fi hàn pé owú jíjẹ, fífẹ́ ìyàwó kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, aáwọ̀ láàrin àwọn èèyàn jẹ́ lára ohun tó ń ṣe àfihàn ìbágbépọ̀ láàrin àwọn ẹ̀dá láwùjọ. Bí àwọn ẹ̀dá kò bá máa ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ara wọn ìwọ̀nyí kò lè ráyè wáyé, bí kò bá sì wáye, a kò ní bá a pàdé nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ bí orin sákárà Òsénì Èjìrẹ́ tí a yàn nínú bébà yìí. Pẹ̀lú àwọn nǹkan tí a tọ́ka sí wọ̀nyí, a lè sọ pé èsò àwujọ̀ ni iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ bí àwọn onímọ̀ ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ-wo lítíréṣọ̀ ti sọ.

## Obìnrin Gẹ́gẹ́ bí i Òpùrọ́/Eléte

Ọkan lára ìwà tí àwùjọ lòdì sí ni kí ẹ̀dá jẹ́ òpùrọ́ àti elétekéte. Ìwà kò tọ́ ni méjèèjì wọ́n sì jìjọ ń rìn papọ̀ ni. Kò sí bí yóò ṣe jẹ elétekéte tí kò ní purọ́, nítorí irọ́ ni yóò fi gbé ète rẹ̀ kalẹ̀. Irọ́ ni kí èèyàn sọ ohun tí kò rí bí ó ti pè é. Yorùbá a máa pa á lówé pé, "purọ́ o níyì, ẹ̀tẹ́ ló máa ń mú dání". Èyí túmọ̀ sí pé, bí èèyàn bá torí kí ó lè gbayì lójú àwon èèyàn purọ́, alábùkù ni yóò padà já sí tí àṣírí irọ́ tó pa bá tú. Ojú kò tọ́ tí Yorùbá fi ń wo òpùrọ́ náà ni Òsénì Èjìrẹ́ fi wò ó. Àpẹẹrẹ èyí jẹ yọ nínú orin "*O-déte-déte*":

LÍLÉ Ò déte déte, ò déte déte

ÈGBÈ Obìnrin ló déte sílẹ̀ látijọ́ aláyé ti dáyé,

Àwọn ni, tẹ bá bi wá léèrè, a ó rálàyé ṣe

LÍLÉ Nígbà àtijọ́, ayé ijọ́hun
Nígbà àtijọ́, bóbìnrin dọ́kọ ẹ̀ níta
Pípa ni wọ́n máa pa á o
Bó bá bá jẹ́, báje bá ṣí lé lórí
Nígbà àtijọ́ láyé láyé
Ẹ wá wète obìnrin, nígbà tó dakọ ẹ̀ níta
Ló bá sáré, ó lọ bá àlè ẹ
O kọ́ lọ́gbọ́n, péun tí ó bá'un ṣe lójú ayé
Ní gbangba, atúnṣe ni kí o bá un ṣe
Ìyàwó bá bọ́ra sílẹ̀, o lọgun ariwo níta
Níjọ́ yẹn, àlè ẹ̀ o wá ń ré kọjá
Kíá-mọ́sá, àlè ẹ̀ ń wá ba róṣọ
Ìgbà tọ́jọ́ ajé kò, gbogbo ayé pé o
Wọ́n ní kíyàwó ó wá búra
Ìyàwó sọ níjọ́ yẹn, Ìyàwó mà ń sọ o
Ó lẹ́nikan ò rí hòhò un, lálái ṣọkọ òun
Àyàfi bùrọ̀dá kan tó gbaun sílẹ̀ níjọ́ aṣọ tú
Àfi yẹn ló tún rí hòhò òun.
Ó ní, tó bá ṣé lórí àwọn méjì, tóun wí yẹn òo, ìwọ ajé
Kíá bí idán ìyàwó da kọjá
Ajé ò mà múyàwó o, ó yege asọkọ dòpùrọ́ ẹ ṣé

LÍLÉ Bó ti lè wù kéte yín ṣe lè ga tó
Ẹ ì ma ṣèbà, ọkùnrin lolórí yín

Àyọlò òkè yìí kò jìnà sí èrò Yorùbá pé, obìnrin tí yóò bá dété-kéte yóò lè pa irọ́. Obìnrin tí Òsénì Èjìrẹ́ gbé ìtàn rẹ̀ kalẹ̀ yìí ṣe àgbèrè pẹ̀lú ọkùnrin mìíràn. Ó tún dá ọgbọ́n kí ọkùnrin yìí kan náà rí ìhòhò rẹ̀ níta gbangba. Ó ṣe èyí pẹ̀lú èrò pé, òun yóò tọ́ka sí i pé ọkùnrin yìí ni ọ̀kunrin mìíràn tí ó rí ìhòhò nígba tí aṣọ òun tú lójijì níta gbangba. Obìnrin yìí mọ̀ pé àgberè ni wọ́n fi ẹ̀sun rẹ̀ kan òun, ṣùgbọ́n ó yí i sí rírí òun nígbà tí aṣọ já bọ́ nígbà tí ó ń búra. Ọgbọ́n àti ètè burúkú ni obìnrin yìí fi bo irọ́ àti ìwà ìbàjẹ́ tí ó hù mọ́lẹ̀. Àpẹẹrẹ mìíràn jẹyọ nínú orin "*Ayé ń yí lọ*" báyìí:

ÀJỌKỌ Ìtàn mi, ìtàn mì, ìtàn mì doorí ò dorí

LÍLÉ Ó wá doorí àwọn ọ̀rẹ́ ẹ́ mẹ́ta ooo...
Àwọn mẹ́ta wọ́n wá jọ ń fẹ́ yàwó kan
Ẹni kìn-ín-ní kò sọ fẹ́nì kejì,
Ẹnì kẹ́ta kò mọ̀

ÈGBÈ Pẹ́nìkan ṣọṣọ ni wọ́n jọ ń fẹ́

LÍLÉ Ẹ wá rí bi ọ̀rọ̀ yìí gbé yaaa

ÈGBÈ Yaa lẹ́gbẹ̀ẹ́ ni, nígbà tí wọ́n rìn débi kan

ÀJỌKỌ O níi jígí i ló gbé jígí sójú uu

LÍLÉ Ló bá ń wo Máàtílẹ́wà oo,
ÈGBÈ Ìyàwó ẹẹ oo
LÍLÉ Níbii tó gbé ń dákú u dájííí,
Ó gbé jígí ẹ fẹ́ni kejì ó wá ń tara ṣàṣà
ÈGBÉ Ó ní kẹ báaun wo ìyàwó òun un
LÍLÉ Lẹnì kejì bá tún gbe sójú
Ó tún ń wo Máàtílẹ́wà oo
ÈGBÈ Ìyàwó ẹẹ oo
LÍLÉ Níbii tó gbé ń dákú u dájííí,
Ó ní, yàwó òun ló wàa nílẹ̀ yìí oo
ÈGBÈ Lẹnì kẹ́ta bá tún gba jígí…
Ó tún ń wo Máàtílẹ́wàaa nílẹ̀ gbọrọgọdọ
Níbii tó gbé ń dákú u dájííí
Ó ní, yàwó òun ló wàa nílẹ̀ yìí oo
Ló bá fi táùdá a sókè, lẹ́ẹ̀mẹ́ta aa…
LÍLÉ Ọ̀rọ̀ yẹn dìjà fáwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta…

Àyọlò òkè yìí náà fi ìwà búburú àti ètè obìnrin hàn àwùjọ kedere. Olórin fi orin òkè yìí sọ ìtàn bí obìnrin kan ṣoṣo ṣe fẹ́ ọ̀rẹ́ mẹ́ta papọ̀, tí àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta kò sì mọ pé obìnrin kan náà ni àwọn jìjọ ń fẹ́. Ìwà tí obìnrin yìí hù burú jáì, ó sì jẹ́ ìwà ìtìjú pátápátá. Ohun ìtìjú ni obìnrin yìí ṣe nítorí àwùjọ kọ̀ ọ́, kò sì lára ìwà ọmọlúàbí rárá. Lóòótọ́ ni alè rí obìnrin tó lè hu irú ìwà báyìí láwùjọ ṣùgbọ́n èyí kò sọ pé gbogbo obìnrin ló ń hu irú ìwà yìí. Ojú-àmúwayé Yorùbá nípa àwọn obìnrin ni ọkọrin yìí gbé jáde lóòótọ́ ṣùgbọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà kò jìnnà sí òtítọ́ àti ohun tó ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ nípasẹ̀ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá tí tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ-wo lítíréṣọ̀ ní kí lámèétọ́ máa yẹ wò nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀. Èyí jẹ́ ọ̀kan lára ìdí tí abala tíọ́rì Louis de Bonald (1754-1840) lórí tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ-wo lítíréṣọ̀ tí ó rí iṣẹ́-ọnà gẹ́gẹ́ bíi díńgí tí ó ń ṣe àfihàn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ̀ tí a yàn fún iṣẹ́ yìí fi tẹ̀wọ̀n tó láti ṣe iṣẹ́ yìí.

## Obìnrin Gẹ́gẹ́ bí Alágbèrè

Ìwà àgbèrè jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìwà tí kò fi ènìyàn hàn gẹ́gẹ́ bí ọmọlúàbí láwùjọ. Àwọn Yorùbá ti lẹ̀ gbà pé àgbèrè ṣíṣe lè mú ikú dá ni. Èyí ló jẹ́ kí wọ́n máa pa á lówe pé "Ikú àlè yíyàn ni yóò pa ọ̀dọ́kọ". Ìtumọ̀ èyí ni pé, obìnrin tó bá ń dọ́kọ tàbí ṣe àgbèrè yóò pàdé ikú lójijì. Àgbèrè ní í ṣe pẹ̀lú níní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ọkùnrin tàbí obìnrin tí kì í ṣe ọkọ tàbí ìyàwó ẹni. Òsénì Èjìrẹ́ bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà kò tọ́ yìí nínú awo orin tó pè ní "*Mójú kúrò*"

LÍLÉ Àǹtí kan wá pè wá lọ sí patí à àlè ri o
ÈGBÈ Àǹtí kan wá pè wá lọ sí patí à àlè ri o
ÀJỌKỌ Bùrọ̀dá kan wá pè wá lọ sí patí à àlè ri o

Bùrọ̀bá kan wá pè wá lọ sí patí à àlè ri o

LÍLÉ À ṣẹ́ni tó ń pè ní sisí

ÈGBÈ Tẹ̀gbọ́n tàbúrò wọ́n ń fẹ́ra wọn

LÍLÉ Ẹni tó ń pè láǹtí

ÈGBÈ Tẹ̀gbọ́n tàbúrò wọ́n ń fẹ́ra wọn…

ÀJỌKỌ Àǹtí kan wá pè wá lọ sí pati à àlè ri o

LÍLÉ Kó má fàlè ẹ hàn wa o é

ÈGBÈ Má fàlè ẹ hàn wa o é

LÍLÉ A ò pé o má ṣe ṣìná o

ÈGBÈ Má fàlè ẹ hàn wa o é

LÍLÉ Àǹtí, a ò pé o má ṣe ṣìná o

ÈGBÈ Má fàlè ẹ hàn wa o é

LÍLÉ Bùrọ̀dá, a ò pé o má ṣe ṣìná o

ÈGBÈ Má fàlè ẹ hàn wa o é

Ọ̀kọrin yìí fi hàn nínú àyọlò òkè yìí pé, ìwà àgbèrè kò mọ láàrin òbinrin nìkan. Bí ó ti wà ní lìkì ló wà ní gbàǹja. Kò sì sí ẹni tí kò mọ pé ìwà kò tọ́ ni, èyí ló sì máa ń mú wọn pàrọ láti bora wọn ní àṣírí. Nínú àyọlò yìí, ó hàn pé obìnrin (*Àǹtí*) àti ọkùnrin (*bùrọ̀dá*) tí Òsénì Èjìrẹ́ ń tọ́ka sí kan ń pe ara wọn ní ẹ̀gbọ́n àti àbúro ni, wọn kì í ṣe ìbátan, àle ni wọn jẹ́ sí ara wọ́n. Èyí fi hàn pé ìfẹ́ ìkọ̀kọ̀ tí kò ṣe é mú yangàn láwùjọ ló ń wáyé láàrin wọn. Àgbèrè àti irọ́ púpa lo jìjọ ń fa ara wọn kọ́wọ́ rìn. Àpẹẹrẹ mìíràn tún hàn nínú orin "*Ẹ rọra pẹ̀gàn mi*" báyìí:

ÀJỌKỌ Ẹ̀sín ilé ẹ̀yẹ, ẹ̀yẹ ìta nìyàwó mà jẹ́ o

KÓlúwa má jẹ̀ ẹ́ kán jẹ wá gbé

LÍLÉ Aaya mi ò sunwọ̀n

ÈGBÈ Torí ọmọ ni mo ṣe fẹ…

LÍLÉ Obìnrin tó ń lọ tó ń bọ̀ lọ́ọ̀dẹ̀ ọkọ o
Bí ò bá para ẹ̀ yóò pọkọ
Ìrò tóbìnrin rojọ́ ọkọ rẹ̀ lọ́dọ̀ àlè
Kò mà jẹ́ rojọ́ àlè rẹ̀ lọ́dọ̀ ọkọ oo
Ọlọ́gbọ́n ayé kẹ́ẹ kíyèsọ́rọ̀ Èjìrẹ́ o

Nínú àyọlò yìí, ọ̀kọrin fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ọkùnrin ní láti gbà mọ́ra, kí ó sì farada ìwà búburú yòówù tí wọ́n lè ní lọ́wọ́ nítorí àǹfààní pọ̀ nínú kí ọkùnrin ní ìyàwó lọ́ọ̀dẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ó fi hàn pé obinrin alágbèrè kò tó láti sọ nípa àlè rẹ̀ fún ọkọ bí ó ti n rojọ́ ọkọ rẹ̀ fún alè. Ojú tí ọ̀pọ̀ èèyàn àwùjọ fi ń wo obìnrin ni Òsénì Èjìrẹ́ náà fi wo obìnrin. Èyí kò jẹ́ ìyàlẹ́nu nítorí inú àwujọ tí obìnrin ń gbé náà ni ọ̀kọrin wà, nígba tí a sì ti gbà pé èso àwùjọ ni orin, ó ti dájú pé ohun tí ó ń lọ láwùjọ ni a máa bá pàdé nínú orin. Bákan náà ni èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Adéyẹmí (2006) tí ó sọ pé, soṣiọ́lọ́jì jẹ mọ́ gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ tó bá jẹ mọ́ ọmọnìyàn

àti ìbáṣepọ̀ láàrin wọn. Ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ àti ìbáṣepọ̀ èèyàn àwùjọ gan-an ni èyí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀.

Ojú àbùkù tí ọ̀kọrin àti ọ̀pọ̀ èèyan láwùjọ fi ń wo obìnrin yìí kò tọ̀nà nítorí obìnrin rere, tí ó gbé orúkọ ìdíle dé ipò gíga pọ̀ níye láwùjọ. Bẹ́ẹ̀ ni obìnrin tí kò mọ ọkùnrin mìíran yàtọ̀ sí ọkọ rẹ̀ kò ṣe é kà tán. Ó hàn pé, "ẹrú kan ló ń múni bú igba ẹrú" àti pé "amúni-kọluni alángbá orí èṣù" ni ọ̀rọ̀ àwọn obìnrin tó ń hùwà kòtọ́ ló mú kí ọ̀pọ̀ àwọn èèyàn láwùjọ máa fi ojú àbùkù wo gbogbo obìnrin tàbí máa fẹnu tàbùkù wọn lọ́pọ̀ ìgbà jẹ́.

## Àgbálọgbábọ̀

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìgbésẹ̀ ni a gbé láti ṣe àgbéyẹ̀wò ojú-àmúwayé àwọn obìnrin nínú àṣàyàn orin Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ tí a yẹ̀wò nínú bébà yìí, a ṣe àyẹ̀wò sí iṣẹ́ tí àwọn ẹni ìṣáájú ti yóò fi ẹsẹ̀ wa lé ọ̀nà tó tọ́, a ṣàlàyé tó yarantí lórí orírun orin sákárà àti àwọn ohun èlò orin sákárà. Ó hàn pé ohun èlò orin sákárà bí i Mólò, Gòjé, Látígò ṣàn wá láti inú èdè Haúsá. Ìdí tí èyí sì fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé, ìpínlẹ̀ Náíjà ni ọmọ Yorùbá tó kọ́kọ́ kọ orin sákárà ti bẹ̀rẹ̀ orin yìí. Àwọn ohun èlò orin tí ó sì wà ní àrọ́wọ́tó rẹ̀ nígbà náà ní ó sì mú lò. Bákan náà ni a yan tíọ́rì ìfojú-ìbára-ẹni-gbépọ-wo lítíréṣọ̀ láti ṣe ìtúpalẹ̀ ojú-àmúwayé Yorùbá nípa àwọn obìnrin nínú àṣàyàn orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́. Abala Louis de Bonarld tí ó tọ́ka pé èso àwùjọ ni iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ àti pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ bí ọ̀rọ̀ obìnrin, ọ̀rọ̀ ìṣèlú, ọrọ̀-ajé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ jẹ́ ohun tí ó lẹ́tọ̀ọ́ kí lámèétọ́ máa wá nínú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ kí ó sì lè sọ bọ́yá òtítọ́ ni irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ tabí irọ́. Ṣíṣe àmúlò àlàkàlẹ̀ àti títẹ̀lé èrò onímọ̀ yìí láti ṣiṣẹ́ nínú bébà yìí jẹ́ kí a rí òkodoro ọ̀rọ̀ tí onímọ̀ yìí sọ pé, èso àti awòjìjí àwùjọ kedere ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Ìdí tí èyí sì fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé ohun tó ń lọ láwùjọ Yorùbá ló ṣara jọ sínú orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni olórin yìí sì ń gbé kalẹ̀ nínú orin sákárà tí ó ń gbé kalẹ̀.

Ní ìparí, iṣẹ́ ìwádìí yìí sọ àsọyán ọ̀rọ̀ pé, orin sákárà jẹ́ àká ìṣelọ́jọ̀ èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá àti lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé, àwọn olórin Yorùbá ti ṣe àgbéga ńlá fún ìpohùn Yorùbá, wọ́n sì ń lò wọ́n láti ṣe àfihàn àti àtúnṣe ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ. Bákan náà, iṣẹ́ yìí tún sọ àsọyán pé orin sákárà máa ń ṣe àfihàn ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ẹ̀dá láwùjọ Yorùbá. Kókó-ọ̀rọ̀ lọ́kan-ò-jọ̀kan nípa ìwà obìnrin ní rere àti ní ìdàkejì tó jẹyọ nínú àwọn àwo orin sákárà Òsénì Ẹ̀jìrẹ́ tí a yàn fi èyí mú lẹ̀, nítorí bí kò bá sí ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí ó hàn nínú àwọn orin wọnyí kò lè wáyé. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a tọ́ka sí wọ̀nyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Caudwell (1977:15) tó sọ pé, ìmọ nípa àjọgbépọ̀ ẹ̀dá lápapọ̀ ni ọ̀rọ̀ nípa soṣiọ́lọ́jì tí a lò nínú iṣẹ́ yìí tan mọ́. Ohun gbogbo tí a tọ́ka sí nínú bébà yìí nípa ìwà obìnrin láàrin àwùjọ fi hàn pé tíọ́rì ìbára-ẹni-gbépọ̀ bá iṣẹ́ yìí mu rẹ́gí.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adégbìtẹ́, A. (2000). "Change and Continuity in Yorùbá Socio-Religious Music" nínú Ọmọ́jọlá, B. (ed), *Music and Social Dynamics in Nigeria.* Ilọrin, University of Ìlọrin, o.i 28-39.

Adéyemí, O. (2006). *Tíọ́rì Lítírésọ̀ ní èdè Yorùbá*. Ìjebú-Òde, Shebiotimo Publication.

Ajíbóyè, O. (2003). *Ewì Alohùn Yorùbá Orin.* Òró: Majab Books, o.i 116.

Akínyẹmí, A. (1986). *Ipò Obìnrin nínú àwọn Eré Oníṣe Akínwùnmí Ìṣọ̀lá*. Trenton, N.J, Africa World Press Inc.

Caudwell, C. (1977). *Illusion and Reality*. London, Lawrence and Osi Chart.

Collins, J. (2002). *African Popular Music: A Historical Review of Sub-Sahara African* (https:en.m.wikipedia.org).

Dáramọ́lá, O àti Jeje, A (1975). *Àwọn Àṣa àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ìbàdàn, Oníbon-Òjé Press & Book Industries (Nig) Ltd.

Euba, A (1971). *Islamic Musical Culture Among the Yoruba: A Preliminary Survey in Essays on Musical and History in Africa.* Wachsmann, Northwestern University Press.

Gbénro A.O. (2001). "Orin Ìbílẹ̀ Yorùbá" nínú *Àkójọpọ̀ Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá.* Ayélàágbé (ed). Ọ̀yọ́: Gibbon & Kee, o.i 44-66.

Ilésanmi T.M. (1998). "The Significant of the myth of women in socio-Political Role Sharing Among Yoruba People" in M.E.M Kọ́láwọlé (ed) *Gender Perceptions and Development in Africa.* Lagos: Arabon Academic Publishers

Laur enson D. àti Swingwood A. (1971). *The Sociology of Literature*. London: Mac Press.

Ògúnṣínà, J.A (1987). *The Sociology of the Yorùbá Novel*. PhD Thesis, University of Ìbàdàn. Okùnadé, A. A (2003). "Images of Lagos in Nigeria Music" nínú *The Evolution and Development of Lagos State* (ed) Rasheed Ajetunmọbi. Lagos: Gabby Printing Nig. Ent. o.i 212-221.

Olúsọjí, S.O (2008). "*Comparative Analysis of the Islam, Influenced Àpàlà, Wákà and Sákárà Popular Music of the Yorùbá*". PhD dissertation, Ibadan, University of Ìbàdàn.

Oyèbámjí, M. (1975). A Literary Appraisal of Sákárà: A Traditional form of Music nínú *Yorùbá Oral Tradition,* Wándé Abímbọ́lá (ed). OAU, Ilé-Ifẹ̀, o.i 517-549.

Rájí, S.M (2014). "*Àgbéyẹwò Ojú Àmúwáyé àti Lítírésọ̀ Alohùn Yorùbá nínú Orin Àjẹmẹ́sìn Mùsùlùmí ní ilẹ̀ Yorùbá*" PhD Thesis, Department of Linguistics and African Languages and Literature, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Ilé-Ifẹ̀.

### Àwo Orin Òsénì Èjìrẹ tí a yàn:

Ìtàn Àwórì (1992) Ọlọ́fin-Àwórì Records

Ò déte déte (1985) Zerato Records

Ìwà-Lẹwà (1980) Zerato Records

Mójúkúrò (1973) Ọlásùnńbọ̀ Records Limited